
# AWON AMI ATI AWON AAMI TI AJEJE

MACMILLAN CANCER SUPPORT

# OHUN TÍ A Ó WÓNÀ FÚN

Kàn sí ibi iṣẹ́ dokità rẹ nípa èyíkéyìí nínú àwọn àmì yìí tí wọ́n bá ntẹ̀ síwájú, wọ́n kò ṣe é ṣàlàyé tàbí wọ́n ṣàjèjì sí ọ.



## Ara Gbígbóná

Ibà tí ó ju 38°C (100.4°F) tí ó wà fún ọ̀sẹ̀ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, tàbí òógùn tàbí àìsàn tí ó wà fún ìgbà pípẹ́ tàbí tí ó sá npadà sẹ́yìn ní gbogbo ìgbà.

## Ikọ́ tàbí ohùn tí ó há

Èyíkéyìí nínú ìwọ̀nyí, tí ó wà fún ọ̀sẹ̀ mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.

## Ìṣòro láti gbé nnkan mì tàbí jẹ nnkan lẹ́nu

Títí dórí jẹ̀díjẹ̀dí tàbí inú kíkún tí ó máa nwáyé fún èyí tí ó pọ̀jù nínú àwọn ọjọ́ fún ọ̀sẹ̀ mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.

## Ìṣòro ti èémí

Ìmọ̀lára èémí tí kò délẹ̀ láìní èrèdí kan.

## Àwọn àyípadà ní ọmú, àyà tàbí orí ọmú

Wíwú tàbí àyípadà yòówù sí ìwòye ọmú, àyà tàbí abíyá rẹ.

## Rírù tàbí sísanra

Títí dórí:

- rírù tàbí àìlè jẹun rẹ dáradára láìní èrèdí kan
- níní ikùn tí ó tóbi tàbí wú síi lemọ́lemọ́ tàbí fún ìgbà pípẹ́.

## Àyípadà inú

Tí ó nwà fún ọ̀sẹ̀ mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, títí dórí:

- nínílò láti túbọ̀ yàgbẹ́ síi tàbí tí ó dínkù síi
- ìgbẹ́ ṣíṣàn (ìgbẹ́ gbuuru)
- ẹ̀jẹ̀ nígbà tí o bá nyàgbẹ́.

## Ìṣòro láti tọ̀

Títí dórí:

- nínílò láti tọ̀ lójijì
- ìrora nígbà tí o bá tọ̀
- ẹ̀jẹ̀ nínú ìtọ̀ rẹ.

## Wíwú tàbí títóbi síi

Níbi yòówù ní ara rẹ.

## Àwọn egbò tàbí egbò inú

- Níbi yòówù ní ara rẹ tàbí ní ẹnu rẹ.
- Tí kò jinná lẹ́yìn ọ̀sẹ̀ mẹ́ta.

## Ìrora

Tí ó nwà fún ọ̀sẹ̀ mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.

## Ẹ̀jẹ̀ yíya tàbí níní egbò

Títí dórí:


- ẹ̀jẹ̀ nínú ìtọ̀ tàbí ìgbẹ́ rẹ
- ẹ̀jẹ̀ nínú itọ́ tàbí èébì rẹ
- nnkan oṣù obìnrin tí ó pọ̀ ju ti tẹ́lẹ̀
- ẹ̀jẹ̀ dídà ní abẹ́ láarín nnkan oṣù kan sí èkejì, lẹ́yìn ìbálòpọ̀ tàbí lẹ́yìn tí nnkan oṣù ti ṣíwọ́
- ẹ̀jẹ̀ nínú omi ara ọkùnrín.

## Rírẹ̀


Níní ìmọ̀lára rírẹ̀ fún ìgbà pípẹ́.

## Àwọn àyípadà àwọ̀ ara

Títí dórí ara sísú tí a kò lè ṣàlàyé rẹ, tàbí èéyi tí:



kò dọ́gba tàbí tí kò ṣe déédé



tí ó ní etí tí kò dọ́gba tàbí tí kò dán



ó ju àwọ̀ kan lọ



ó fẹ̀ ju milimità mẹ́fà lọ



iyipada ni iwọn, apẹrẹ tabi awọ, awọn ara nyún tabi ẹjẹ, tabi erunrun

Àwọn àwòrán yìí wá láti wẹbsaìtì ti National Cancer Institute (**cancer.gov**).

**Diẹ ninu awọn aami aisan jẹ soro lati sọrọ nipa, fun apẹẹrẹ odidi kan lori iṣan rẹ tabi ẹjẹ ti obo. Ṣugbọn paapaa ti o ba jẹ itiju, o ṣe pataki lati ṣayẹwo.**

**O lè béèrè láti rí dokità rẹ lọ́kùnrin tàbí lóbìnrin tàbí nọọsì, ṣùgbọ́n èyí lè má ṣeéṣe nígbà gbogbo.**


## NJE O NI AAMI KANKAN?

**Ti o ba ni awọn ami tabi awọn aami aisan, jẹ ki dokita rẹ ṣayẹwo wọn.**

Fun atilẹyin, itọsọna tabi alaye diẹ sii, pe Macmillan ọfẹ lori **0808 808 00 00**, ọjọ meje ni ọsẹ, lati ago mẹjọ owurọ si ago mẹjọ ni alẹ, tabi se abewo si **macmillan.org.uk**

© Macmillan Cancer Support, February 2020. 3rd edition. MAC15200_E03_Yoruba. Atunyẹwo igbero ti o tẹle ni osu keji 2023. Atilẹyin akàn Macmillan, ifẹ ti a forukọsilẹ ni England ati Wales (261017), Scotland (SC039907) ati Isle of Man (604). ti o tun nṣiṣẹ ni Northern Ireland.

# ÌGBÀ ÀTI BÍ A Ó TI RÍ ÀMÌ KAN YẸ̀WÒ



**Gbogbo ìgbà ni kí o máa gba ìmọ̀ràn láti ibi iṣẹ́ dokità tàbí nọọsì rẹ tí o bá ní àwọn àmì tí ó wà síbẹ̀, tí a kò lè ṣàlàyé tàbí tí ó ṣàjèjì sí ọ:**

**Ó ntẹ̀ síwájú** – àmì kan tí ó pẹ́ ju ọ̀sẹ̀ mẹ́ta lọ.

**Tí a kò lè ṣàlàyé rẹ** – àmì kan tí kò ní èrèdí tí ó hàn.

**Ó ṣàjèjì** – àyípadà kan ní ara rẹ tí kò ṣe déédé fún ọ.

## Àwọn ìṣítí fún bíbá dokità tàbí nọọsì rẹ sọ̀rọ̀

**1.** **Ronú nípa ohun tí o fẹ́ sọ.** Ó lè jẹ́ ìrànlọ́wọ́ láti kọ àwọn àlàyé yìí nípa àmì tàbí àyípadà náà sílẹ̀:

- ohun tí ó jẹ́
- ìgbà tí ó bẹ̀rẹ̀
- bóyá ó jọ ti àtẹ̀yìnwá kan
- ohunkóhun tí ó nmú kí ó sàn tàbí burú síi
- ipa tí ó ní lára ìgbé-ayé rẹ ojoojúmọ́.

**2.** **Nigba miiran o ṣoro lati ṣe eto lati pade ati pe o lenilo lati pe diẹ sii ju ẹẹkan lọ.** Ṣùgbọ́n tẹ̀ síwájú títí da ìgbà tí o ó gba ààyè kan sílẹ̀. O lè gba ààyè ọlọ́jọ́ pípẹ́ sílẹ̀ bákan náà.

**3.** **Mú ẹnìkan dání pẹ̀lú rẹ fún àtìlẹ́yìn.** Ó lè sọ pé kí ẹni náà tẹ́tí sílẹ̀ tàbí kí ó kọ nnkan sílẹ̀.

**4.** **Sọ̀rọ̀ kí o sì tẹ́tí sílẹ̀. Gbìyànjú láti:**

- ṣàlàyé àwọn àmì náà bí o ti rí i sí
- dahun ibeere eyikeyi ni otitọ bi o ṣe le
- béèrè tí o bá nílò ìfitónilétí síi tàbí nnkan kan kò yé ọ
- kọ awọn akọsilẹ, tabi ṣe awọn akọsilẹ lori foonu rẹ.

**5.** **Rii daju pe o mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ tókàn.** Eyi le pẹlu:

- ìgbà tí ó yẹ kí o gba ààyè míràn sílẹ̀
- ibi àti ìgbà tí ó yẹ kí o máa retí ààyè gbígbà sílẹ̀ lọ́dọ̀ dokità akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ kan tàbí fún àyẹ̀wò kan
- ẹni tí o ó kàn sí tí o bá nílò ìfitónilétí tàbí àfikún àtìlẹ́yìn.

**6.** **Ṣe àtúnsọ ohun tí ó yé ọ.** Èyí njẹ́ kí wọ́n lè ṣàlàyé ohunkóhun tí ó bá rú ọ lójú.

**7.** **Rántí, ní ọ̀pọ̀ ìgbà àwọn àmì kìí ṣe ohun tí ó yẹ kí a fòyà nípa wọn.** Ṣùgbọ́n tí àwọn àmì tí a kò lè ṣàlàyé rẹ̀ bá npadà sẹ́yìn tàbí kò sàn síi, gba ìmọ̀ràn lẹ́ẹ̀kan síi. Pe ibi iṣẹ́ dokità rẹ kí o sì béèrè ìmọ̀ràn nípa ohunkóhun tí kò bá dá ọ lójú.

© Macmillan Cancer Support, February 2020. 3rd edition. MAC15200_E03_Yoruba. Àgbéyẹ̀wò tí ó kàn tí a ní lọ́kàn ní Oṣù Kejì, Ọdún 2023. Macmillan Cancer Support, àjọ aláanú tí a fi orúkọ rẹ̀ sílẹ̀ ní England àti Wales (261017), Scotland (SC039907) àti the Isle of Man (604). A nṣiṣẹ́ ní Northern Ireland bákan náà.

**Tí o bá ní èyíkèyìí nínú àwọn àmì inú ìwé ìléwọ́ yìí, gba ìmọ̀ràn láti ibi iṣẹ́ dokità tàbí nọọsì rẹ. Iwọ ko padanu akoko ẹnikẹni. Wọ́n wà níbẹ̀ láti ṣe ìrànlọ́wọ́.**

**Tí o bá ní ìfòyà nípa ṣíṣe àyẹ̀wò àmí kan, pè wá sórí 0808 808 00 00.**

## NJE O NI AAMI KANKAN?

**Ti o ba ni awọn ami tabi awọn aami aisan, jẹ ki dokita rẹ ṣayẹwo wọn.**

Fun atilẹyin, itọsọna tabi alaye diẹ sii, pe Macmillan ọfẹ lori **0808 808 00 00**, ọjọ meje ni ọsẹ, lati ago mẹjọ owurọ si ago mẹjọ ni alẹ, tabi se abewo si **macmillan.org.uk**

© Macmillan Cancer Support, February 2020. 3rd edition. MAC15200_E03_Yoruba. Atunyẹwo igbero ti o tẹle ni osu keji 2023. Atilẹyin akàn Macmillan, ifẹ ti a forukọsilẹ ni England ati Wales (261017), Scotland (SC039907) ati Isle of Man (604). ti o tun nṣiṣẹ ni Northern Ireland.